# Àwọn Ìbèèrè tó Nwáyé Léraléra

## Àkíyèsí nipa Gbigba Ìwífun-ni ti Ìdákọ́nkọ́

Iwífun-ni lori Fọ́ọ́mù Ẹlẹyàmẹyà ati Ìran jẹ ìwífun-ni ìdákọnkọ nipa awọn akẹkọ. Awọn Ìbèèrè tó Nwáyé Léraléra wọnyi sàlàyé idi ti Ẹka Ètò Ẹkọ ti Minnesota (MDE) se ngba iwifun-ni yi; ti o bá ni lati pèsè iwifun-ni náà; bi a ó se lò ó; ati ẹlòmiran wo ló tun le lò ó.

## Kini'dí ti a fi ngba ìwífun-ni yi?

Ni 2017, Ilé Igbìmọ Asòfin Ìpinlẹ Minnesota pàsẹ fún àwọn agbègbè ati awọn ìpín láti gba ìwífún-ni akẹkọ ni kíkún lóri ìran mẹrin ninu ìsọrí mẹfa ti ìran ati ẹlẹyàmẹyà ti Ẹka Ètó Ẹkọ U.S. gbé kalẹ fún àwọn ẹgbẹ pàtó. Fún ìwífún-ni ni kíkún, tọkasi [Minnesota Statutes 2017, 120B.35, subdivision 3](https://www.revisor.mn.gov/statutes/?id=120B.35) (https://www.revisor.mn.gov/statutes/?id=120B.35).

Ete gbigba ìwífún-ni ni kíkún lóri ìran tàbí ìwífún-ni ẹyà ìsẹdálẹ ni láti ni òye tó dára àti láti ni ìdánimọ ètò ẹkọ ti gbogbo awọn akẹkọ ni Minnesota nilò. Àwọn ẹgbẹ wọnyi tó pọ lẹkùnrẹrẹ ni ó hàn gbangba nipasẹ Minnesota State Demographer Minnesota State Demographer tó dúro lori [U.S. Census Bureau's classification/coding system](https://www.census.gov/topics/population/race/about.html) (https://www.census.gov/topics/population/race/about.html). Ìwífun-ni lati mọ ẹgbẹ tó pọ jùlọ tó ni asojú wá lati Àwùjọ Olùwádi Amẹrikà ninu àgbékalẹ détà ti ọlọdun kan tabi ọlọdun márùn-ún. Fun ìwífún-ni siwaju si, tọkasi oju ewé [American Community Survey](https://www.census.gov/programs-surveys/acs/) (https://www.census.gov/programs-surveys/acs/).

## Ìgbà wo ni a ó gba ìwífún-ni yìí?

Ọdun ilé-ìwé 2018-2019: Bíbẹrẹ si gbigbà ìwífún-ni ni kíkún lóri ìran tàbí ìwífún-ni ẹyà yóò kọkọ sẹlẹ ni àwọn aládugbò agbègbè márùn ún: Community of Peace Academy, Minnetonka Public Schools, Schoolcraft Learning Community, St. Paul Public Schools, and Worthington Public Schools. Ó se é se ki àwọn aládùgbò agbègbè yi fi fọmù ránsẹ láti gba détà látilélwá ni ìgba sọ́mà/fọ́ọ́l ti ọdún ilé-ìwé 2018-2019 pẹlú ifọwọsowọpọ pẹlu àwọn fọ́ọ́mù ìforúkọsilẹ fun ọdun ile-iwe ti 2018-19. Àwọn agbègbè aládùgbò márùn ún yìí tabi awọn ìpín yóò firòhin lẹkùnrẹrẹ akẹkọ nipa ìtilẹ̀nde tàbí ìwífun-ni ẹyà ìsẹdálẹ ránsẹ si Ẹka Ètò Ẹkọ Minnesota (MDE) ninu ọdún ilé-ìwé 2018-2019.

Látàrí àwọn ẹkọ ti wọn kọ pẹlú àwọn aládúgbò agbègbè márùn ún tabi ìpín náà, ó se é se ki gbogbo àwọn agbègbè ati ìpín miràn fi ránsẹ silé ẹdà ìmúgbòòrò gbigba détà fọ́ọ́mù náà ni fọ́ọ́lù/wíntà ti ọdún ilé-ìwé 2018-2019 pẹlú àwọn fọ́ọ́mù ìgbaniwọlé fún ọdún ilé-ìwé 2019-2020.

Ọdun ilé-ìwé 2019-2020:  Gbogbo àwọn agbègbè ni a ó pasẹ fun láti fi ìròhìn  ìwífún-ni ni kíkún lóri ìtilẹ̀nde tàbí ìwífún-ni ẹyà ìsẹdálẹ ránsẹ si ẹka náà ninu ọdún ilé-ìwé 2019-20.

Ìwífún-ni yi ni a ó gbéyẹwò ti a ó si mu bá igbalode mu ni ọdọọdún márùn-ún bẹrẹ láti igbà ti gbogbo agbègbè bá ti bẹrẹ si sisẹ le lóri, pẹlúpẹlù àwọn àkọ́kọ́ agbègbè aládùgbò, bẹrẹ ni ọdún ilé-ìwé 2024-25.

## Sé ìdílé kọọkan ni wọn ni kó dáhùn àwọn ìbéèrè yìí?

Bẹ́ẹ̀ni.  Fun ọdún ilé-ìwé 2018-2019, ìdílé kọọkan pẹlú akẹkọ kan ninú ọkan lára àwọn aládùgbò agbègbè tó nlọ si ipele K-12 ni a nsọ fún láti dáhùn àwọn ìbéèrè wọnyi. A tún le sọ fún òbí kan lára àwọn aládùgbò agbègbè láti fílì àtúnkọ fọọmù lọdún tó nbọ, bi ẹka ti ntẹsiwájú láti má a se àfikún ìjábọ látọdọ àwọn ará ìlú sinú fọọmù náà.

Fun ọdun ile-iwe 2019-2020 gbogbo agbegbe Minnesota ni yóò má a sọ fun gbogbo idile lati fílì fọọmù pẹlú awọn ẹgbẹ ni kikun.

## Ti awọn ìdílé kò bá pari fọọmù náà nkọ?

Awọn ile-iwe nilati ròhìn iwifun-ni ìran ati ẹlẹyàmẹyà  fun ipinlẹ ati si Ẹka Ètò Ẹkọ ti U.S.  A kò reti ki o pèsè iwifun-ni yi funrarẹ sugbọn ti o kò bá sé, ofin àpapọ reti ki o yàn funrarẹ.  Ti awọn idile kò ba fílì fọọmù náà, *awọn agbegbe ni a reti lati yanjú awọn ibèèrè lori ìran/ẹlẹyàmẹyà, ni làsàsà*, tó dúro lori iwifun-ni tó dára julọ ti wọn ni ki wọn si fi iwifun-ni náà sọwọ si Ẹka Ètò Ẹkọ Minnesota (MDE).

Awọn abala fọọmù náà ti kò pọn dandan ni wọn ko le gba lọwọ rẹ, bẹeni a kò reti awọn agbègbè lati se pinnu ni kikun awọn kódù ti ìran/ẹlẹyàmẹyà.  Ti o kò bá pèsè ìwífún-ni yi, awọn ile-iwe ati MDE kò ni mọ nipa awọn ẹgbẹ awọn akẹkọ ni pàtó wọn si le máse danimọ ati ba aini eto ẹkọ pade ti ẹgbẹ awọn akẹkọ.

## Àwọn Ibèèrè Làsàsà

Àwọn ìbéèrè làsàsà ni awọn ibèèrè àpapọ tó nbèèrè nipa ìran/ẹlẹyàmẹyà.  A mọ rírì ìjabọ náà wipe ìran ati ẹlẹyàmẹyà jẹ agbékalẹ àwùjọ atipe àwọn itumọ yi yatọ.  A ntẹlé itọni àpapọ ni sísàmi si ọkọọkan.

Awọn kódù mẹfà ti ìran àpapọ/ẹlẹyàmẹyà farahàn gẹgẹbi awọn ibèèrè “Bẹẹni/Bẹẹkọ” lori fọọmù náà, tó si pẹlú ibèèrè ni ti ẹlẹyàmèya loke ati Awọn Ìbèèrè Kini titi de Ikẹfa. Ìkójọ lápapọ ìwífun-ni ti ìran/ẹlẹyàmẹyà nilo ìbéèrè kan tó pin si méjì.  Ìbèèrè tó wà lókè nbèèrè ti akẹkọ náà bá jẹ Hispanic/Latino. Ijọba àpapọ gbà pé Hispanic/Latino jẹ ẹyà kan. Àwọn ibèèrè yókù (Ikini, Ekeji, Ẹkẹta, Ẹkẹrin, Ìkarùn-ún, ati Ìkẹfà) nílò, ó kéré tán, lati yan ọkan ninu awọn wọnyi:  Amẹrikà India, Asia, dúdú tabi Afrikà Amẹrika, Ọmọ ìbílẹ Hawai tabi Erékùsù Pasifiki, tabi funfun. Ìjọba àpapọ gbà pé awọn ẹgbẹ wọnyi jẹ awọn ìran.

Àwọn ìdílé kò nilati yan ọkan ninu àwọn isọri wọnyi.  Ti wọn kò bá se bẹẹ, awọn agbègbè nipa ofin lasẹ lati dánimọ̀ ki wọn si ròhìn iwifun-ni yi fun awọn akẹkọ látàrí iwifun-ni didára ti wọn ni silẹ.   A fun awọn Agbègbè lásẹ lati gba iwifun-ni tó yẹ fun gbogbo awọn akẹkọ nipa lilo ọkan lara àwọn ilana yi ni lẹsẹẹsẹ:

A. idánimọ̀ òbí tabi alágbàtọ;

B. idanimọ̀-ara ẹni ti akẹkọ pẹlu ọjọ-ori tó yẹ, nigbàti idánimọ̀  obi tabi alágbàtọ kì í se bí mo bá fẹ;

C. ti àwọn ọnà idánimọ̀ ara-ẹni ni ti obi, alágbàtọ, tabi akẹkọ kò bá se é se, fífojú-kà nipasẹ ọgá àgbà tabi asojú rẹ, lábẹ iwé itọni ti agbegbe náà gbé kalẹ.

## Àwọn Ìbèèrè Bi-mo-ba-fẹ

Àwọn ìbéèrè ti a kà si bi-mo-bá-fẹ nbèèrè fun iwifun-ni ni kíkún ni ti ìran/ẹlẹyàmẹya.  Gbigba iwifún-ni yi kì í se, imúyẹ apapọ kan. *A kò reti awọn agbègbè lati se ipinnu ni kikun lori àwọn kódù ìran/ẹlẹyàmẹyà.* A ngba ìwífun-ni yi nitori ẹkúnrẹrẹ ti a fi sinu Awọn Ofin Minnesota 2017, 120B.35, subdivision 3 gẹgẹbi a ti jiròrò loke ninu abala "Kini'dí ti a fi ngba ìwifun-ni yi?"  Awọn ìsọri bi-mo-bá-fẹ ni:

- Anishinaabe/Ojibwe; Cherokee; Dakota/Lakota;  American Indian Asopọ Ti Ẹyà Miran
- Asian Indian; Burmese; Chinese; Filipino; Hmong; Karen; Korean; Vietnamese; Asian Miran
- African-American; Ethiopian-Oromo; Ethiopian-Miran; Liberian; Nigerian; Somali; dúdú, Miran
- Colombian; Ecuadorian; Guatemalan; Mexican; Puerto Rican; Salvadoran; Spaniard/Spanish/Spanish-American;  Hispanic/Latino Miran

## Ríròhìn

Iwifun-ni ninu Ìbeerè àkọ́kọ́ ati awọn Ìbéérè keji si ikẹfà kò ni àsopọ pẹlu ináwó ìpinlẹ. Ti idílé kan ba yan Hispanic tabi  Latino, a o ròhìn akẹkọ gẹgẹbi Hispanic tabi  Latino si ipele apapọ. Fun àpẹẹrẹ ti akẹkọ kan ba farahàn gẹgẹbi Hispanic tabi Latino ati funfun, a ó ròhìn wọn gẹgẹbi Hispanic or Latino ninu ilana isiro. Ti idile kan bá yàn ju ọkan lára iwọnyí: Amẹrika India, Asia, dúdú tabi Afirika Amẹrika, Ọmọ Ibilẹ Hawaiian/Erékùsù Pasifik, tabi funfun a o ròhìn akẹkọ náà si ipele àpapọ gẹgẹbi "ìran meji tàbi jù bẹẹ lọ." Fun àpẹẹrẹ, ti a bá fi akẹkọ hàn gẹgẹbi Amẹrikà ati India tabi Ọmọ Ibilẹ Alaska ati funfun, a ó ròhìn wọn gẹgẹbi "ìran meji tabi jù bẹẹ lọ" ninu ilànà isirò. Ẹgbẹ yi ni a sábà má a ntọkasi gẹgẹbi kódù keje ìran/ẹlẹyàmẹya àpapọ kò si hàn gbangba lóri fọọmù.

A bèèrè lọwọ àwọn akẹkọ ni Ìbéèrè Kini ti wọn bá farahàn gẹgẹbi Àmẹrikà India tàbi Ọmọ ibilẹ Alaska.  Ẹgbẹ èniyàn yi ni ipinlẹ Minnesota túmọ si àwọn èniyàn tó wá láti ìran ọkan lára àwọn àtilẹ̀bá èniyàn ti Àriwá Amẹrikà ti wọn si di mu sinsin àmì àsà ìdánimọ nipasẹ ifaramọni ti ẹya tàbi ìdánimọ àwùjọ.  Iwifun-ni yi ni a ròhìn rẹ lápapọ ti a si tún lò láti sirò àtilẹhin ipinlẹ.

## Kini ìdí ti a fun awọn ẹgbẹ kan ni ààyè lati yan níní àwọn ẹgbẹ kíkún, sùgbọn àwọn miràn kò ni ààyè?

Àwọn ẹgbẹ kikun náà ni Minnesota Statutes 2017, Section 120B.35, subdivision 3 (https://www.revisor.mn.gov/statutes/?id=120B.35) ndari rẹ̀

Lábẹ ofin yi, "Ọmọ Ìbílẹ Hawai tabi Erékùsù Pàsifiki Miran" ati "funfun" ni a kò fun ni ààyè yíyàn lati ròhìn ju ẹkúnrẹrẹ awọn ẹgbẹ. Labẹ ofin ìpinlẹ ti ise détà, [Minnesota Statutes 2017 Section 13.05, subdivision 3](https://www.revisor.mn.gov/statutes/?id=13.05) (https://www.revisor.mn.gov/statutes/?id=13.05), MDE ni lati fi ìdiwọn si gbigba, lilò ati pinpin iwifun-ni idákọnkọ nikan si ohun tó yẹ lati sakoso ati mójútó awọn progirámù ti a fọwọ si ti ijọba àpapọ si fàsẹ si.

## Báwo ni a ó se gba ìwífun-ni yi?

Lati fun gbogbo ìdilé ni ààyè lati dára wọn mọ ni pàtó, awọn agbègbè le yàn lati gba ìwífun-ni náà ni awọn ọnà tó bá àsà ati èdè wọn mu. Awọn agbegbe ni a rọ̀ lati fi fọọmù ti a fi ngba iwifun-ni ati lẹta obi ransẹ sile pẹlu akẹkọ kọọkan.

## Ti awọn ìdílé bá ti nlo awọn isọ̀ri ti atijọ nkọ?

Ti àwọn ìdílé ba ti pèsè iwifun-ni yi lori awọn fọọmù ti àtẹhinwá, a nsọ fun wọn lati fi fọọmù náà silẹ lẹẹkan si. Idi ni wipe awọn idile ti pèsè ìwífun-ni yi tẹlẹ ni lilo awọn fọọmù ti atẹhinwá, wọn wa nsọ fun wọn lati fi fọọmù náà silẹ lọ́tun. Idi èyi nipe Ẹka Ètò Ẹko ti Minnesota nse iyipada si awọn ilana bi wọn se ngba iwifun-ni. Gbogbo ìdílé ni a gbọdọ fun ni ààyè lati pese lẹkunrẹrẹ iwifun-ni ni ti ẹlẹyàmẹyà ati ìran yálà lori iwe tabi lori ẹrọ.

## Bawo ni wọn yó se lo iwifun-ni yi ni ipele ìpinlẹ?

Iwifun-ni akẹkọ rẹ kọọkan jẹ idákọnkọ, ati pe MDE nikan ló lẹtọ lati lò ó labẹ ofin. Ti a ba ròhìn iwifun-ni a o ròhìn nipa awọn ẹgbẹ, kì í se nipa awọn akẹkọ kọọkan.

- ẹkúnrẹrẹ iwifun-ni ti ìran/ẹlẹyàmẹyà ni a o lò fun gbigbà ati rirohin iwifun-ni ni ipinlẹ.
- Ni ìbámu pẹlu ofin ipinlẹ, Ẹka Ètò Ẹkọ ti Minnesota nsètò lati ròhìn iwifun-ni yi ni ipele ẹgbẹ fun iwifun-ni ti àyẹwò ati ìkẹkọ gboyè fun ọdún kini. Irohin ọjọ iwajú le fikún ipele ẹgbẹ iwifun-ni fun awọn ami idagbasoke, imúrasilẹ fun iwe kika siwaju si lẹhin iwe ile-iwe giga ati awọn ààyè lati sisẹ, ààbò ile-iwe, ati àsopọ akẹkọ pẹlu ile-iwe.
- Iwifun-ni akẹkọ kan ni ti ìran/ẹlẹyàmẹyà ni a o papọ pẹlu ipò pàtàki akẹkọ yẹn, ipò ìkẹkọ Oyinbò rẹ, akọ tabi abo, ati awọn iwifun-ni miran. Awọn irohin ọjọ iwájú le pèsè irohin ẹgbẹ to fi ààyè gba oniruuru àkópọ tabi awọn àsàyàn iwifun-ni yi. Fun àpẹẹrẹ, gbigba iwifun-ni yi yóò fi ààyè gba ifiwéra iye awọn tó kẹkọ gboyè fun ọkunrin Chinese ti kì í se akẹkọ Òyinbó si akẹkọ obirin Somali tó jẹ akẹkọ Òyinbó.
- Ni ìbámu pẹlu ise iròhin MDE, a kò ni kọ irohin fun ẹgbẹkẹgbẹ tó bá dín ni awọn akẹkọ mẹwa, pẹlú awọn èsì nibiti ẹgbẹ awọn akẹkọ yokù ti kéré si mẹwà. Ìròhin-ki-rohin tó bá dá lori ẹkúnrẹrẹ iwifun-ni ìran/ẹlẹyàmẹyà yi yóò lo ofin itẹriba ipele keji ti MDE fẹ gbe jade tó si fẹ bẹrẹ si lilo ni osù Kejila ọdun 2018.

## Bawo ni a ó se lo Ìwífún-ni yi ni ipele agbègbè?

Fun Ìwífun-ni siwaju si nipa bi a o se lo iwifun-ni yi ni ipele agbegbe jọwọ kàn si [awọn] ọfisi agbegbe rẹ.

## Se a ó ròhìn iwifun-ni yi fun ijọba àpapọ?

Àfi iwifun-ni ti ìran/ẹlẹyàmẹyà nikan ti a bèèrè fun lápapọ lara awọn ìbéèrè làsàsà (Amẹrikà India tabi Ọmọ Ìbílẹ Alaska; Asia; dúdú tabi  Afrikan Amẹrikà; Hispanic/Latino; Ọmọ Ìbílẹ Hawai tabi Erékùsù Pasifiki; funfun) ni a ó ròhìn si ijọba àpapọ. Ẹkúnrẹrẹ iwifun-ni ẹlẹyàmẹyà (ti a tọkasi gẹgẹbi bi-mo-ba-fẹ) kò ni jẹ irohin ti a ó fi sọwọ si ijọba àpapọ. Ìwífun-ni yi ni a ó diwọn rẹ ni awọn ọnà wọnyi:

- A kò ni ròhin iwifun-ni yi si gbangba ni ipele akẹkọ kọọkan.
- Iwifun-ni yi kò ni jẹ àsopọ pẹlu ipò ìsilọ-silùú-mìí ni ipele ìpínlẹ tabi àpapọ a kò si ni yẹẹ́wò nibòmiràn.
- Iwifun-ni yi kò ni i se nkankan boya akẹkọ rẹ le lọ si ile-iwe.
- Niwọn igbàti a gba iwifun-ni yi fun akẹkọ kọọkan, a o rohin rẹ nigbangba fun awọn ẹgbẹ akẹkọ nikansoso.  Àwọn irohin tí ẹka náà pèsè wà lati dábòbò idanimọ akẹkọ kọọkan, ati pe ẹgbẹ akẹkọ náà gbọdọ tóbi tó jẹ wipé a kò ni le dá akẹkọ kọọkan mọ̀.
- Iwifun-ni yi kò ni sopọ mọ isẹ tabi àyẹwò olùkọ.
- Iwifun-ni yi kò ni nkankan lati se pẹlu wiwọlé ile-ẹkọ giga.

## Taani yóò ni ààyè si iwifun-ni yi lábẹ’lé?

Fọọmù yi ati iwifun-ni ti o wà ninu rẹ̀ ni a o kó jọ sinu awọn ilana iwifun-ni latọwọ ẹnikan tó ni asẹ ati idánilẹkọ ni ọfisi alabojútó ti akẹkọ rẹ. Òsisẹ ile-iwé tó ni ojúse lati ri si kikọ ati kikójọ àwọn fọọmù náà, le wo awọn fọọmù ti wọn ti kọ bi wọn ba ti nkó wọn lọ si ọfisi alabójútó.

## Taani ẹlòmiràn tó tún le ni ààyè si iwifún-ni yi?

Awọn ile-iwé ati Ẹka Ètò Ẹkọ ti Minnesota (MDE) gbọdọ fi idiwọn si níní ààyè si iwifun-ni ti a pèsè lori fọọmù náà nitoripe ó jẹ idákọnkọ.  Awọn tó le ni ààyè si pẹlu:

- Ile-iwe ati òsisẹ MDE ti ó nilò lati ni ààyè si iwifun-ni náà lati se isẹ wọn;
- ẹnikẹni ti o fun lásẹ lati ni ààyè si iwifun-ni náà; ati
- ẹnikẹni ti ipinlẹ tabi ofin àpapọ fun lasẹ lati ni ààyè si iwifun-ni náà.